## ASAYAN ORO

Ẹwurẹ wo alapata, bi ki o ku. Awodi wo igbin kọrọ. Kini ẹiyẹ oko yio fi Igbin ṣe ? Ori l'o niṣẹ ẹda l'a yanmọ.

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WON KO ṢE WI L'EJO

## Akiysi Pataki

A fiwe yi ṣe ikede si awon Aṣoju iwe irohin Eleti-Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, enikẹni ti ko ba fi owo ti o ti je ranṣẹ si wa, a o pe lejọ, ako si ni fi iwe irohin ranṣẹ si enibe mọ.

VOL. XI No. 637. LAGOS. SATURDAY, AUGUST 15-AUGUST 21, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)


# Yegede! Lagos Town Council Jare.

**Abọ iwadi ọrọ owo ọja ti Ọgbẹni Beyioku ṣe aṣiwaju olufisun wipe awon igbimọ Lagos Town Council gba lọwọ awon obinrin ọja lọna aitọ, ti ijọba Apapọṣe yan ọgbẹni R. N. Rapson Oyinbo lati ṣe iwadi na ni abọ rẹ jade.**

**Ọgbẹni Rapson si ṣe iwadi ọrọ na kini-kini, o si ri wipe, Lagos Town Council ko jẹbi ọrọ na. Ọkan ninu awon obinrin ọlọja ni a gbọ wipe, o rojọ bayi pe bi nwon ba patẹ, Town Council yio le won, bi nwon joko, Town Council yio le won, bi nwon kiri ọja bakanna ni nwon ma le won.**

**Gbogbo awon obinrin ọlọja wa kebosi lọ ba Town Council wipe ki nwon ko ọja si Idumagbo fun won. Nwon dahun wipe ko si owo ti ijoba fi le kọ isọ na fun won. Ibẹ ni awon ti panupọ lati da owo jọ ni apo ara wa, ki nwon le ba wa fi kọ isọ na.**

**Ọgbẹni Rapson ṣiro gbogbo owo ti nwon ti ngba, owo na si pe pere-pere. Ṣugbon igbimọ nla ti Ijọba Apapọṣe ko fi ara mọ idajọ Ọgbẹni Rapson, nitorina nwon ni ki igbimọ Lagos Town Council lọ da owo pada fun olowo.**

**Awon obinrin olọja dahun wipe, ko nṣe owo ni awon nbukata, Isọ ibiti nwon gbe ma ri aye ta ọja won ni nwon fẹ.**

## "ẸMI ỌGA" D'OLOGE

EKO. A gbọ jugbanu ni irohin ti a gbọ ni alẹ ọjọ Monday ọsẹ yi wipe arabinrin kan ti oruko rẹ njẹ Wulemọtu Adelakun (eniti ọpọ enia mọ adape rẹ gẹgẹbi "Ẹmi Ọga") ṣ'alaisi ni ile rẹ ni Isalẹ-Eko.

Ẹgba ni arabinrin na, ko si nṣe ẹniti a le fi ọwọ rọ s'ẹhin ninu awọn ti o nta pangolo ati igo ni Oke Arin tabi Kosọkọ Street, L'Eko. Ologbe yi ko ju ọmọ ọdun mẹrindinlọgọta lọ, ki oto fi aiye silẹ.

Ọpọlọpọ awọn obinrin alaṣọ ati onigo pẹlu awọn oniṣẹ Iwe Irohin Eleti—Ọfẹ dabira nibi oku na. Adupẹ lọwọ awọn arabinrin bi Muniratu (alias Wuudia Ofin) ati awọn ẹgbẹ alaṣo ti o nawo-nara nibi oku rẹ, papaa, a dupe lowo Councillor Taju Thompson, Managing Director, Iwe Irohin, Eleti-Ọfẹ fun inawo rẹ. Ki Olorun jẹki tiwa na dara o.

"Ẹmi Ọga" Ọrun rere.

No. 119


# Inland Waterways Department
## NOTICE No. 24 Of 1959.

### SAPELE/BENIN FERRY SERVICE

**With reference to I W D Notice No. 21 of 1959, it is notified for general information that the nomal service with two vessels will operate on or about the 22nd August, 1959.**

C. ATKINSON
DIRECTOR
Inland Waterways Department


## Oro Asoje Ile Igbimo Lori Iwadi Owo Oja



OLOYE AKINTỌLA



OLOYE BALOGUN

Nigbati awọn igbimo mẹnu kan oro Lagos Town Council ninu ipade won, nwon sọ pe nwon ko faramọ iwadi Ọgbẹni Rapson.

Ibẹ ni Kola Balogun ti oju rẹ ko gbe ibikan dahun pe on kan sara si ijoba Apapose nitoripe bi nwon ko ba ko abo iwadi na jibiti iba ma gberu si nilu Eko.

Oloye Akintola dahun pe bi oro na ba bi awon ninu ki nwon lo pe ejo si kotu. Kola Balogun so pe, bi o ba jẹ pe on ni Rapson ti o ṣe iwadi ọro na, on iba fi ọlọpa mu ninu awon enia na.

Oloye Akintola dahun pe iwo kẹ Kola Balogun, abajo ti nwon ta o nipa jade kuro ninu ẹgbẹ N.C.N.C.

## IJỌBA GBE OHUN ARA DE FUN AWON MẸKUNNU

Ijọba tun ṣẹṣẹ gbe ara kan de nisisiyi fun awon oṣiṣẹ tabi ẹnikẹni, yala Agbẹ tabi oniṣẹ Ijọba. Ijọba ile Hausa ti ṣe adehun pẹlu awon Oyinbo Oniṣowo kan ti nwon nkọ ile ta.

Ẹniti ko ba lowo lọwọ lati fi kọ ile onibiriki tabi ile onibulọku, bi o ba ti ni owo bi iwon adọta ponun, ọgọrin poun, tabi ọgọrun ponun, nwon o fi patako kọ ile kan gẹgẹbi owo re bati mọ ranṣe si ọ lati Ilu Oyinbo wa.

Nigbati ile na ba de, iwọ yio ranṣẹ pe Kapinta ki o wa kọ ile ọongalo na sibiti o ba fẹ. Bi o ba si jẹ oṣiṣẹ ni ọ, nibikibi ti o ba nlo ni iwọ yio tun gbe ilẹ rẹ lọ, aye ti o ba si wu ọ ni iwọ yio kọ si.

## Okunrin Kan Ju Okuta Fun Onigbese

ENUGU. A w ọ n ọlọpa mu ọkunrin kan duro ni waju Adajọ fun ẹsun wipe, o ba ẹnikan ja. Adajọ pe ọdaran na, o bere pe, kilo fa ija wa?

Ọdaran na dahun wipe, ọkunrin ti on ba ja yi jẹ on ni gbese ogun Pọnun ko si fẹ lati san'wo yi mọ. Nitorina, nigbati mo ri ı, inu bi mi nitori ti o nfi mi ṣe fari, mo ki okuta mọlẹ, mo si ju lu u ni ojugun.

Adajọ bere pe kiniṣe ti o fi ju lu, o dahun pe bi mo ba sọ oko lu bẹ yio wa lu mi pa, nigbana ko ni si ẹniti yio sin ni gbese mọ. Eyi ni ejọ ti ọkunrin ọdaran na, ti orukọ rẹ njẹ Mathew ro.

Nigbana ni adajọ dahun wipe, bi o ti wu ki o ri, ọdaran yi ko ni aṣẹ lati gbe idajọ le ara rẹ lọwọ nitorina ki o lọ san Pọnun mẹdogun tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu meji.

## ỌPỌLỌPỌ AWỌN ORILẸ-EDE LO NI IFẸ RERE SILẸ NIGERIA

EKO. Ọkan ninu awọn Minister i l ẹ Gẹsi, Lord Perth sọ nilu Eko laipẹ yi nigbati o ti sokalẹ kuro ninu ọkọ ofurufu ni Ikẹja wipe ogidinleje ninu awọn orilẹ ede lo ni ifẹ rere si ilẹ Nigeria kakiri orilẹ agbaiye

Eyi fihan iru iwa ti ilẹ Nigeria yio ni ati iru iṣe ti nwon o se lẹhin ti nwon ba ti gba ominira. Wiwa ti on wa yi, a ran on wa lati wa se ,ofintoto Ilẹ Nigeria fun ọse meta pere, gẹgẹbi oro ti on gbo lẹnu Festus Okotie-Eboh.

Lord Perth tun fi enu k a n oro Atom Bombu ti Faranse fẹ ju sinu Sahara. O wipe, on ko ni gbagbo wipe etu oloro ti awon Faranse fe ju yio se jamba rara. Nitoripe awon ti ba Ijoba Faranse soropo nipa oro na nwon si ti fun wa ni-ideri wipe ẹtu oloro ti nwon fe ju yi ko ni ṣe jamba kan.


E MA KA

IWE IROHIN

ELETI-OFE

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN


## Eni Meta Ja Lori Tani Ya Oro Julo.

### APA 3

Lati Ọwọ AROKIN

Lẹhin t i ẹsin ja kulẹ ninu idanwo ti Ọbatala fun won, ni Ewurẹ bọ sita, o nwa Ọrọ lọ. Bi o ti tun de ikorita, ibẹ lo ba Onile, Ewure duro kiji, o wipe jọwọ dide ba mi kalọ o jare, nitori iwọ na ni mo wa titi de ihin.

Ọrọ na bere tan, ran ọ simi, Ewurẹ dahun pe, tete da mi lohun o jare, nitori bi o ti ya ọrọ ni emi na ya, Ọbatala lo si npe ọ. O ya oro na lẹnu lati ma gbo iru oro nwonyi. O bere pe bawo ni ọro tirẹtiri o jare, orẹ, Ewurẹ dahun pe, bi mo ba bimo loni ẹsẹkanna ni yio bere si rin.

Ọrọ na dahun pe si o! iru eyini ni a npe ni oro bi? Ma lo, nko wa. Bi Ewurẹ ti yo lokere ti o nsare bo jẹkete-jẹkẹte Ọbatala m i s i ẹhin pe boya o nmu oro na bowa' ṣugbon pabo n i gbogbo rẹ gbogbo awon eran ile si hobo Ewure.

Bẹni Adiẹ fo pẹrẹ lati ori aba o si nsare lo ni opopo, bi o ti d e ikorita bẹni o ba Onile. Adiẹ kesi wipe, Ọrọ fun-n-n Ọrọ na nfẹ ma sore, nigbati adie ja n i koro wipe, b i iwo yio ba kalo k i o tete kalo, nitori Oyun mi mbe nilẹ.

Nigbati oro na gbo wipe, oyun kan wa nilẹ, o ni on yio lo f i oju kan oyun ti o ngbe ile na. Lati ojo na wa ni adiẹ ti gba ori bi oro ba nkoja, adie yio wi, bi ko ba si ohun ti adiẹ ti ko ni kigbe.







Kẹre o!

A ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO

BROTHERS

MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAM

28, K... Street, Lagos. — "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL. XL NO. 637. SATURDAY AUG. 15 AUG. 21, 1959


## Obe L'omu Agba.

Ọrọ owe oke wosika wa ọsẹ yi ni a fẹ ṣe alaye le lori fun ẹnyin ọkawe wa, gẹgẹbi ọrọ owe na ti mọ niba soki yi, ki iṣe ọrọ kekere rara, ọrọ pataki ni iṣe. O tọ, a si yẹ ki awọn obi ọmọbinrin mu ọrọ onjẹ sise ni okunkudun fun awọn ọmọ wọn obinrin nitoripe awọn ti o yio jere bi nwọn ba mọ ọbẹ sise, aiko mọ ọbẹ sise yio mu wọn ke abamọ.

Nitori iṣe ti adidun ọbẹ kole ṣe pelu ọkọ ti o ba fẹ obinrin ti o mọ ọbẹ se daradara ati eyiti ko mọ se, ti a fi wipe "Pademi-ni-gbọnwọ" ọbẹ ni o nse fun ọkọ je. Ki a maṣe gbagbe wipe pupọ ninu awọn ọkunrin ni nwọn "Iya ọlọbẹ" adin ṣinṣin s'ọkọ l'ẹnu ti fi ọbẹ gba ọkọ lọwọ awon ti ko mọ ọbẹ se.

Nitorina, ẹkọ pataki l'ojẹ fun ọdọmọbinrin lati ni ẹkọ onjẹ sise daradara, nipa bẹ yio gbadun ọkọ ti o ba fẹ, yio si tun ni'yi ni ọjọ ti ase ba kan lode larin awọn obinrin ẹlẹgbẹ rẹ.

Leto, ọkundun ọkunrin wa, ṣugbọn bi a ba fẹ sọ ododo ọrọ, ko si ẹniti a le fun ni onjẹ adidun je ti ko ni fẹrẹmo obinrin na pẹki-pẹki. Tabi ẹwẹ, bi okunrin ni iyawo rẹ ko mọ ọbẹ se ba jaja lo ṣe alabapade obinrin miran sibi ti nwọn ma njẹki ọbẹ ma sọ. "Tapa lori ina, "malai talat" ọkọ na ko ni ranti iyawo rẹ ni isiko ti o nfi kọtọ s'ara.

E ma gbagbe, ẹ ranti pe ọbẹ l'ọmu agba.






# Alase Ile Igbimo (House Of Assbly)



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni omoba Adeleke Adedoyin ti o jẹ ọmọ bibi inu Ologbe Alaiyeluwa Akarigbo ilu Rẹmọ, Ijẹbu. Adedoyin ti a nwo aworan yi ni Alaṣẹ ti o mbẹ lori aga igbimọ (House of Assembly) nilu Ibadan.




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.


## Ole Ja Olori Ijo Aguda

A gbọ wipe Ọlọṣa kan gboju-gbaiya lọ ja ojiṣẹ Olorun ni ole, on ni Olori Ijo Aguda, Alufa Ẹniowo Leo Taylor, nwon ji ẹro akorin rẹ lo, eyiti awon Fadi obinrin ti Ijo Abẹokuta fi ta lore nigba ajodun odun kẹdogbon ti o ti joye Olori Alufa Ijo Aguda.




# Olopa Ti O Seleri Arede Kuna Ileri re

Obinrin Ọlọmọge kan ti o njẹ Janet lo pe Ọkunrin Ọlọpa kan lẹjọ wipe, o şeleri fun on wipe a yafi bi on ba le tẹra silẹ ki on kọja, nigbati ọrọ na ba di oyun ni on yio to gbe mi ni arede.

Nitotọ ọrọ na di oyun de ipoti mo fi bimọ na fun u, lẹhin na lo tun wa nlọ tikọ-tikọ lati gbemi ni arede nitoripe o ba aiye mi jẹ o si fẹ ja mi silẹ ni ofege ki adajọ ba mi gba ọdunrun ponun lọwọ rẹ.

Ọkunrin Ọlọpa na gba wipe nitotọ ni on şe irufẹ ileri bẹ fun ọmọge na, şugbọn on ko figba kan ba sọ pe on koni mu ni arede mọ. Ohun ti o fa ti ko jẹki arede na ti ya ni wipe, awọn obi rẹ sọ wipe, bi a ba fẹ gbeyawo arede na nilu wọn ni Onisha ni ki nwọn wa şe.
Şugbọn on ko ri aye nisisiyi lati lọ si Onitşha nitoripe lẹnu işẹ ijọba ni on şiwa akoko ko si ti de ti mo ni lati gba aye isinmi ti mo le fi ri aye lọ si Onitsha lati lọ gbeyawo gẹgẹbi awọn obi rẹ ti fẹ. Nigbana ni adajọ yẹ ẹjọ na si igbamiran.

# Oloye Awolowo Nile India



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni akoko igbati Oloye Awolọwọ lọ bẹ ile India wo. Berẹ lati ọwọ ọtun ni Oloye Awolọwọ ti o mba Ọgbẹni Nehru sọrọ, ẹniti o şe ẹkẹta wọn ni Oloye A. M. A. Akinloye ti o nwo awọn mejeji bi nwọn ti nsọrọ lọwọ

## NWON ŞA OBINRIN KAN PA SINU ILE

EJIGBO. Obinrin abileko kan ti orukọ rẹ njẹ Morenikẹ Abeo onişowo atara ni işẹ, o si lowo lọwọ dara-dara. Ni ọjọ Alamisi (Thursday) ni awon olopa ri oku rẹ ninu agbara ẹjẹ lẹgbẹ ibusun ọmọ rẹ ti ọjọ ori rẹ ko ju odun mejila lọ, ati omo na ti nwon ti sa logbe ninu agbara ẹjẹ bakanna.

Nwon yara gbe omo lo sile Iwosan ni Oshogbo fun itoju nitoripe keiti ku. A gbo wipe esẹ kan aiye ẹsẹ kan orun ni omo na wa.

Awon olopa lero wipe awon olosa to lẹ ko ile obinrin na lo şe işẹ aidara yi. Nwon ti da enia meje duro si Kotu lati se iwadi wo.

## E Toju Aja Nyin

Ijoba şe ikilo bayi wipe, ki awon ti o ba ni aja nile mase gba awon aja na laye lati ma ringba-nraye kakiri igboro, nitoripe nwon le ko jamba ba enia ti o nrin lọ loju Titi. Enikeni ti o ba mo pe on ko le toju aja rẹ, o san ki o ma kuku sin aja rara.

Larin ọdun ti arun Digbolugi pọ aja mejidiladọta ni awon ri arun na lara rẹ, nwon ri lara Ologbo mefa ati lara enia meta. Ẹdẹgbẹrun aja ni ijoba gun ni abere nitori arun digbolugi, sugbon ẹdẹgbẹrin ricu won lo gba iwe aşẹ (Licensed). Nitorina aja ti ko baiti gba nisisiyi, ki awon maşe jafara lati gba tire.

Awon majẹmaja yio bẹ sode nisisiyi lati ma mu awon ti ko ba gba iwe, eyiti nwon ba ri, o di mimu, eyiti o si lọ fi pamo eyiti awon ko ba si wa gba titi ọjọ meta, ijoba yio pa danu.

Nitorina, ki gbogbo eni to ni aja lọ gbawe fun aja won, nitoripe aja ti o ba ti gbawe, ko si ewu fun nẹ.

## IGBIMO NI A ŞE IPADE AJALO ARUNGBE

EKO. Igbimo nla (House of Representatives) se ipade Igbimo ikẹhin ti ati fi toka, ti an si şe idibo yon siro ti yio şe ebo toko Ijoba ernaira ile Nigeria ni owo ati owo, ni alafia ati ilera, ni ohun gbogbo ti o dara fun ile awa enia dudu, ile Nigeria.

Diẹ ninu ofin ti nwon fe şe ninu igbimo na ni, bi nwon o ti şe fun omo ogun oju omi ilẹ Nigeria ni suna, lati tun ofin Ijoba ibilẹ Ekọ (Lagos Town Council) şe lati tun ofin ẹkọ şe lati se ona ti a ngba yan ọba Eko, lati gba aşẹ Ijoba wipe, gbogbo ọba ti o ba jẹ nilu Eko ninu Iga Idunganran ni ki nwon ma jẹ si, lati ma yan Oloye ati lati ma fi enia joye ati bẹ bẹ.

## Itan Awon Omoba Meje

(Apa 10)
Lati Owo Arokin

Nigbati ile ọjọ keji mọ, Oba Ọlọfin ran awọn ẹmẹwa rẹ pe ki nwọn lọ pe Akanbi Ọmọba Ọrangun ile Illa wa. Inu awọn mejeje na dun pe, Ọlọfin tun fẹ pa ọmọba na. Ṣugbọn, nigbati ọmọba Illa nlọ da ọba lohun awọn ọmọba Ọlọfin meje na ṣe Akiyesi wipe, o di ohun kan kurudu sinu aṣọ. O wa bẹrẹ si ṣe wọn ni inu fu ẹdọ fu wipe, boya o ri wọn tabi ko ri wọn.

Bi Akanbi ti de waju ọba o dobale pelu ẹrin. Ọba Ọlọfin wa ṣe Akiyesi pe boya, nkan na ti jọ fun ọmọba Illa o yara bere pe Ẹja ni tabi akan? O si yara dahun, pe Kabiyesi, akan ni. Bẹ lo gbe ohun ti o di sinu aṣọ silẹ, o tu u, o fi ewe fadaka lele lọtọ, o fi ife Wura silẹ lọtọ, omi odo ti o mbẹ ninu aja'lẹ ti o rọ sinu igo, o fi lelẹ. Oruka wura ti nwọn bọ si ori tabili, ti o mu bọ wa'le, o fi le lẹ.

Lehin ti o fi gbogbo rẹ lelẹ tan, Akanbi sọ fun Ọlọfin pe ki o ranṣẹ pe awọn ọmọba na ki nwọn wa jeri pe ododo ni gbogbo rẹ. Ọlọfin tun bere pe, o da nyin loju pe ododo ni gbogbo ọrọ na nwọn tun dahun pe ododo ni.

Nigbana ni Ọlọfin pe Akanbi moro, o si fi ọwọ pa lori, o ni ki o mu eyiti o wu u ninu awọn mejeje o si lọ mu aburo won abigbẹhin.

Lehin igbeyawo ọlọfin jin o si bun ni ebun papọ

---

### ẸNITI O NṢE OWO RO-BI-RỌBI FUN ENIA LỌ GB'EWA.

ABA. Okunrin Aiapata kan ti oruko rẹ nje Nnam Oko ni a gbo wipe, o lo se owo robirobi ni owo Kọrenṣi oni ponun kokan ti at jo ti a lo ri bi oni Ponun marundinlogoji, o si nṣe si Ṣile-ṣile ni biti o gbe nla eran ni arin oja ilu Aba. Enikeji re ti o 'nlọ ṣẹ owo na kakiri ni Augustine Nwankwo.

Adajo bere wipe, e jebi tabi e ko jebi nwọn dahun pe nwon jebi nighana ni adajọ sọ pe nigbati e ti mo pe, ẹ jẹbi, ese ti e ko fi jewọ obun ki a ba le da aṣọ bo nyin? Nitorinu ki enikokan nyin lọ gbewa odun marun-marun.

---

### OKUNRIN KAN BẸ ORI ENIA NI OKITIPUPA

AKURE. Ẹjọ ti nwon ro ninu kotu nla nilu Akure ni pe, Ijoye kan seleri Ponun marun fun eniti o ba le gbe ori enia wa fun on, nwọn si ge ori enikan nitoto

Ọkunrin apania na funra rẹ lo rojọ bayi wipe on pelu awon meji to duro ti on yi lo jijọ gbimọ po lati pa ọgbẹni kan ti o nje Igbekele Akinmeji nilu Gbekebọ leti Okitipupa.

Awon ti o jẹ isongbe rẹ ni Dele Stephen, Felex Akingboye ati Tata loge awon mẹteta jẹ ọmọ ilewe. Bi ejo na ti lọ niyi. Ijoye ilu Gbekẹbọ kan ti o nje Koloboye seleri ponun marun fun on bi on ba le gbe ori enia wa fun on. Okunrin ọdaran na wa lo gba awon ọmọ ilewe lati ran lowo.

Nigbati ọkunrin ti nwon fe pa na mbo lati oko, nwon fo mọ, nwon si bẹ lori. Dokita ti o ṣe ayẹwo oku na sọ pe nigbati nwon gbe oku na de, ko ni ori rara, apa ọgbẹ si pọ lara rẹ.

Ọdaran na sọ fun Adajọ pe, ko nṣe oju lasan ni on fi ṣe iṣe buruku yi on lero pe alijannu kan ni o mba ja lakoko na. Adajo da awonomọ ilewe na sile lojukan ni ọdaran apania na gba adajọ rẹ.

---

### ỌKUNRIN KAN JI ỌMỌ GBE NI APAPA.

APAPA. Ọmọkunrin kan to nje Amadu O... ro ni a gbọ wipe o lo ji omobirin kan todoro-do ni ojo ... jegunle, ni apapa, ni ojo ... osu April to koja lo yi 1959.

Ajinigbe yi wa lati ilu Kwale ni agbegbe Asaba, lati wa bere ise buruku yi eniti o si koko ri ji gbe ni odomobirin kekere kan ti o nje Muniratu omo odun merin ni apapa.

Ọkunrin odolughelu yi je agbalagba ti odun ori re nlu bi iwon adota odun, a si gbo pe ninu ile ti Ijoba ko fun awon osise Marine ni odaran yi ngbe. Adajo so pe, on gbe ejo na lo si kotu odaran nla (Assize).

---

# Ominira Ile Nigeria Daju



Awon merin ti o mbẹ ni iduro ti a nwo yi, lati ọwọ osi, Dr. Nnamdi Asikiwe, Oloye Ọbafẹmi Awolowo, Sir Lennox-Boyd ati Sir Ahmadu Bello, Sardauna Ṣokoto. Awon mẹrin nwonyi ni yio gbe ilẹ Nigeria de Ominira eyiti a nreti lati gba ni ọdun 1960.

---

## Olotu Ijoba Apapose



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Alhaji Tafawa Balewa ti o jẹ asiwaju gbogbo awon Premier gegebi Olotu ijoba apapọse nilẹ Nigeria. On na si pẹlu awọn enia ti yio gbe wa de Ominira ni ọdun 1960 lẹhin ti a ba dibo ti ao di ninu ọdun yi ti olukuluku wọn ba wọle.

---

## Ole Ko Eru Makoli Ni Ibadan

IBADAN. Ọdọmọkunrin kan ọmọ odun mejidilọgbon ti oruko rẹ nje Johnson Oyedele ni a gbọ wipe, o sopanpa papọ pelu ọkunrin kan ti o nje Olu Ọsoba, lati jijọ lo fo ile Ọgbeni Milton Makoli ni ojo 24th oṣu July 1959.

Eru ti nwon ri ko to ologorun poun, Johnson Oyedele dahun pe, on jebi niti on adajo ni ki o lọ si ẹwọn ọdun meji ṣugbon Olu Ọsoba ni ki adajọ ṣe on jẹjẹ nitori pe on ko jebi ninu oran na. Adajọ paṣe wipe ki awọn ọlọpa maṣe gba iduro rẹ ki nwon fi si ipamo titi ojo Friday 28th August 1959, ki a to ma ba ọrọ rẹ lọ. Ile Milton Makoli ti nwọn lọ fọ na mbẹ ni Jeriko nitosi ile Alaisan.




## Awon Egba Ko Iramo Ofin Ijoba Iwo-Orun

ABẸOKUTA. Ọgọta ninu awọn Ijoye Ologboni ti Abẹokuta, awọn Parakoyi awon Imole ati awon Kiriyo ti o mbẹ ni Abẹokuta ati agbegbe rẹ lo panupọ ti nwọn kọ iwe ẹbẹ si Oloye Ọbafemi Awolowo, Olotu Ijoba Iwo-orun ilẹ Nigeria, ati si Alhaji D.S Adegbenro Alabojuto Ijọba Ibilẹ ni agbegbe Iwọ-orun Ilẹ Nigeria wipe

Ofin ile bibaya ti nwọn ṣe fun ilẹ Ẹgba, ko tẹ awọn lọrun, nitorina ki Ijọba ba won mu ofin na kuro. Awon ara Abẹokuta dahun pe, iwe ti won ko yẹn ko nṣe wipe nwọn fi ni ion meji si Alhaji Adengbero bikoṣe si igbimọ Ijoba Ibilẹ Ẹgba ti o mbẹ ni abẹlẹ to ni ki awọn sọ ọrọ na di ofin mọ wọn lori.

Apejuwe ti awọn Ẹgba ṣe ni wipe, nwọn ṣe ofin na nitori ki nwọn le ri aye gba ile kuro lori talaka. Ile gbigbe nilẹ Ẹgba ko ni owo lori gẹgẹbi ti ibomiran bi Eko ati Ibadan, nitorina bi Ijoba ba fi tipẹ-tiẹlẹ mu ofin yi yio so pupọ ninu awọn enia di alaini ile lori.

## Ikomojade Miringindin

Ko ni gbagbe ni ọjọ ọsẹ (Sunday) ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu August 1959, nigbati Ọgbẹni K. O. Giwa ṣe ariya ase ikomọ-jade awọn ọmọ rẹ marun ni adugbo Adu Street, l'Eko. Orukọ awọn ọmọ na ni Sulaimon Abiodun, Ayisatu Adesọla, Ramọtalai Adebisi, Faosatu Abẹbi ati Risikatu Mojisọla

Awọn elere meji ni o fi ilu ati orin wọn da awọn enia lara ya titi di ọganjọ oru ọjọ na. Awọn Ọgbẹni Aka Ọnisakara ati Tunji Onijeju. Awọn enia ti baba awọn ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ lọrun le ni ẹdẹgbẹta.

Diẹ ninu awọn enia pataki ti a le darukọ ni Oloye Eletu Odibo, T.S. Fuja Arẹ Eko, Dr. Oni Akerele I.O Bajulaiye, Adeyẹkan Williams, Saka Mọgaji, K. Oshodi, Sergt. Major. Tade, Councillor Adulere ti Ibadan ati S F Adebiyi.

Ire a kari o

# Ebun Egberun Ponun

# Fun Orin Orile-ede Wa

## (National Anthem)

### The Words Of The National Anthem Are as follows:

1. Nigeria, we hail thee,
Our own dear native land,
Though tribe and tongue may differ,
In brotherhood we stand,
Nigerians all, and proud to serve
Our Sovereign Motherland.

2. Our flag shall be a symbol
That truth and justice reign,
In peace or battle honour'd,
And this we count as gain,
To hand on to our children
A banner without stain.

3. O God of all creation,
Grant this our one request,
Help us to build a nation
Where no man is oppressed,
And so with peace and plenty,
Nigeria may be blessed.

Ijọba Apapọse tilẹ Nigeria fi ẹbun ẹgbẹrun pọnun lelẹ fun ẹniti o ba le kọrin orilẹ-ede tilẹ Nigeria.

Ki ese orin mẹtẹta jẹ ohun orin kanna, ki o si ba awọn ọrọ orin na mu regiregi.

Ki iwe orin kọkan si jẹ ohun orin kanna de'lẹ. A ko ni da awọn iwe orin ti a ba ri gba pada, gbogbo re yio wa ni ikawọ Ijọba Apapọṣe.

Ẹ fi awọn iwe ranṣẹ si :-

**THE INDEPENDENCE CELEBRATIONS Officer, 34/36 Ikoyi Road, Lagos**

Ki esi kọ bayi si ẹhin apo iwe na, "NATIONAL ANTHEM". Ao jẹki ẹ mọ bi a ba ri gba.

OJO TI A KO NI GBAWE MỌ **NOVEMBER 30, 1959**

Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 28 Kosọkọ Street P.O. Box 467 Lagos. Phone 23370